# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL. XIV 854 LAGOS SATURDAY JANUARY 26 - FEBRUARY 1st 1963 KOBỌ MEJI (2)


## OJU A RI TO !

# Baba Aladura Kan Fi Posi Oku Se Ile

AMẸRIKA—Kosi ibiti eṣe ko si, ọgbẹni aladura kan ti o ti jẹ ọbẹ adidun ti o ti yo bi olokugbẹ ni a gbọ irohin wipe o ni ki awọn ẹmẹwa on gbe on ninu posi oku (coffin) lọ si iwaju adajọ kotu agba ilu Nashville ni Amẹrika lati lọ jẹri nipa onijibiti kan ti o fi ailowo ni Banki ti o nfun wọn ni iwe owo eru lati fi san gbese kiri.

Nigbati baba aladura na ti o pe ara rẹ ni "Biṣ ọbu Onimariwo" (Bernard Swain ni orukọ ti awọn obi rẹ sọọ) de iwaju adajọ ninu posi oku ti o kajọ si adajọ na ni kilo rọ luu, o ni on riran wipe ki on gba'wẹ ni ogoji ọsan ati ni ogoji oru ninu posi na ni; ọjọ na ko si ti pe rara ki on to ri iwe akọwe kotu gba wipe ki on wa jẹjọ lori ọrọ Ọgbẹni ti o lu on ni jibiti pọnun meji abọ pere.

Adajọ na ni ori rẹ ko ba pe, t'on pe nitoripe gbogbo nkan ti baba aladudura na nṣe yi ẹlẹya ati kari mi ni on mọọ si. ..ojokọjọ ti o ba ri wipe ori on ti FA EPO ki o pada wa si iwaju on lati wa sọ t'ẹnu rẹ.

Lọgan, awọn ọmọ ẹhin baba aladura na ti gbee nilẹ pẹlu posi bi oku ti nwọn ngbe lọ si itẹ lati lọ sin pada si ile adura rẹ.

## Janduku Gun Olopa 'Badan Lobe Pa

Ibadan. Gbogbo awọn enia ti nwọn wa sere ni hotẹli kan ni Ibadan ninwọn tuka nigbati ọkunrin onijagidi-jagan kan gun ọlọpa ijọba kanti o njẹ Mọmọdu Abu lọbẹ pa nibiti o gbe nlaja fun awọn janduku meji ti o mba ara wọn ja loru ana.

Onirohin wa ni ọrọ oṣelu ko ṣelu ni o da ija awọn janduku mejeji na silẹ nibiti nwọn gbe nja ija yi lọwọ ni ọlọpa na ba wọn nibẹ, ti o da si; nwọn ni didasi yi ko tẹ ọkan ninnjwọn lọrun, eyi ni o mu ki o fa ọbẹ yọ, o si fi gun Abu.

---


## LAGOS RACE CLUB

The Annual General Meeting will be held on Thursday 31st January, 1963 at 5 P.M. at J. K. Randle's Memorial Hall, Tafawa Balewa Street, Onikan Road, Lagos, MEMBERS ONLY. Members badges to be produced to gain admission.


## AWON SOJA GB'ODE NILU TOGO

### Nwon Le Awon Onirohin Jade

LOMẸ— Bi ẹ ba fẹ ki ẹ gbọ, ọrọ iku alamojuto ijọba ilu Togo, Dokita Olympio ti awọn ọlọtẹ yinbọ pa laipẹ yi fẹ bi'ge b'adubi nilu Lomẹ ati gbogbo igberiko Togo, ọga awọn ṣọja ti o ditẹ pa alakoso Ijọba wọn na, ti orukọ rẹ njẹ Kofi Kongo ti le gbogbo awa akọwe irohin patapata kuro nilu Togo. O ni Olofofo ni wa, o ni gbogbo nkan ti awọn nṣe ni bonkẹlẹ ni a ntẹ fun gbogbo agbaiye jade bẹni awọn ku fi iṣẹ rẹ ran wa.

Pẹlu ibẹru ni mo fi nkọ irohin yi nibiti mo gbe de si nitoripe gbogbo irohin ti a ba fẹ fi ranṣẹ si ile ni awọn ọga ṣọja na ni ki nwọn ma yẹwo, owo waya paapa ti lewo si fun awa oniwe irohin. Ọrọ awọn Oyinbo oniwe irohin paapa ko ta lọdọ awọn ṣọja ilu Togo na mọ, gbogbo wọn ni nwọn ni nwọn ti ha niwe pe ki nwọn jade nilu awọn patapata.

Ọkan balẹ tuntun, Ọgbẹni Grunitzky ti awọn ọlọtẹ yan ni alakoso Ijọba Togo paapa ko ba lẹ nibiti o gbe nbe. Lojo ti o ti gbọ irohin wipe gbogbo awọn orilẹ ede ilu Afrika jake jado fe se ipade l'Eko lori ọrọ ilu on ati bi Dokita Olympio ṣe ku ni o ti nwo'le wọ'de pẹlu ọga awọn ṣọja rẹ ati awọn amugba lẹhin rẹ.




(Wo yoku loju ewe kejọ)

# Awon Ṣoja Gb'ode Kan Ni Togo Ati Ghana

AFLAO (Bode Ghana-Togo) Ogun lọgọ awọn sọja ati ọlọpa ilu Aganyin (Ghana) ni Dokita Kwame Nkrumah tiṣe alakoso ilu na ti pasẹ wipe ki nwọn lọ duro si oju ala awọn ati awọn ara ilu Togo pẹlu ibọn ati agba wipe nwọn ko gbọdọ jẹki ọmọ ilu Nigeria kan, ko ba ṣe Hausa ni, Yoruba tabi Ibo ni, wọ'lu rara.

Onirohin wa ni lati ọjọ keji ti awọn ọlọtẹ ti lu Dokita Sylvanus Olympio, alakoso ilu Togo pa ni alamojuto ilu Ghana na ti ko awọn sọja ilu rẹ wa ro soju ọna bi ẹniti o fẹ ba ẹnikan ja'gun, iwa ika ti awọn ṣoja ati ọlọpa na nhu ko ṣe fi ẹnu wi.

Nkan kekere ni a kọ pe ọrọ na, a fi igbati awọn onisowo ara ilẹ Nigeria ti nwọn nko nkan tita, bi iṣu, elubọ ẹyin-awo gari ati alubọsa lọ si Accra de ninu awọn mọto akẹru, ti awọn sọja wipe KO SI ỌNA fun wọn rara lati gba kọja.

Kekere ni adanu ti awọn alalubọsa pa lọdọ awọn Hausa ti nwọn fi mọ-tọ jankan jankan ko malu lọpọlọpọ wa si bode na, ti nwọn si mbẹbẹ lọdọ awọn sọja wọnyi wipe ki nwọn jẹ ki awọn malu na kọju ki nwọn ma ku si awọn lọrun.

Esi ti awọn sọja Ghana na fun awọn onisowo ilu Nigeria ni "ẹnyin ko gbọdọ gbe ilu yin ni ? Inu eyiti a ko si yi ni a o mọ orilẹ ede ti o lagbara ju ikan lọ".

Ọpọlọpọ malu ti nwọn nko lọ si Ghana na ni nwọn ti bẹrẹ si ku, awọn apo alubọsa paapa ti bẹrẹ-si ra ti nwọn si nsa wọn ninu orun. Gbogbo awọn onisowo ti ọna semọ yi ti sọ Aflao di ibugbe sugbọn onjẹ ko si nibẹ rara.

## Oloye Ojikutu Mba Itan Awon Alapata Lo

"Mo ni o yẹ ẹni gbogbo ko leni loko ko yẹ pakọkọ abẹkọ lẹnu; bi gbogbo enia yio tilẹ ditẹ si wa ko yẹ Ọgbẹni Shittu ọmọ baba wa Sunmọnu Ayilara. A mọ wipe awọn ọmọ Ibadan ko baa ni, ṣugbọn ti o ba ronu atẹhinwa, ti ko nṣe majẹni enia ko yẹ ki o papọ pẹlu wọn rara.

"O ya mi lọnu pupọ pe e le gbagbe pe ọtẹ bi iru eyi lo gbe idaji isọ baba lọ ni ọjọ kinni ati pe nigba isọ keji fẹ bọ lọwọ baba na, baba wa l'agbo ile Jagun ti o njẹ Lawani Ọttun ti o nṣe iṣẹ telọ ni baba ologbe wa na yan si mi pe ki o bẹ mi, ki njọwọ, ki nma jẹ ki isọ kanna ti o ku yi bọ lọwọ on.

"Baba wa Ologbe na si tun ran iyawo rẹ ti o njẹ Odee si emi alara pẹlu bakanna. Arabinrin na si wa laiye ni isọ ẹran ti o nta ẹran, orogun iya Shittu yi si ni.

"Mo si gbiyanju nigbana, ṣugbọn nigbati a ri wipe awọn Onimọtoto (M.O H) igbana ko fẹ gba ti baba Ologbe, awa yi na ni a fi orukọ Shittu rọ ipo ti baba na lọjọ na; M.O H. na si gba fun wa. Bi Shittu ṣe di alapata ati oni isọ ni ọjọ oni ni yio.

"Ṣe kiṣe on nikan ni baba yi bi lọmọ ki a to fi eyi da a lọla, ṣugbọn iya rẹ ti o njẹ Mọriamọ jẹ Onisowo wa nipa rira ori malu ti a npa lọjọ na fun tita. Họwu, ore pẹ aṣiwere gbagbe. Bi enia ko ba mọ ọrẹ ta, ṣebi o si yẹ ko mọ wipe ẹniti o ba fun ni a fun !

"Bi ọmọ wa yi ba ronu jinna ko yẹ ki o pẹlu awọn ọmọ'badan ditẹ si wa nitoripe nigbati mo fi aṣẹ si ẹran pinpin fun pipa l'Eko awọn ọmọ Ibadan kanna yi ni nwọn kọ lati pin ẹran sile baba wa Ologbe Ayilara na.

"Emi ni mo pa a laṣẹ pe ki nwọn lọ pin ẹran fun Shittu, nwọn ni ki i ṣe alapata rara; gẹgẹbi baba ẹgbẹ ati olori alapata, nwọn si mu aṣẹ mi ṣẹ. Nitorina ọrọ Shittu Ayilara yi dabi ọrọ alangba ti o fi jingin soju, kinni yio fi wo ti o ju ogiri lọ.

Iyoku di ọsẹ ti mbọ.

## OKO AFEFE TUNTUN



Awọn Olotu ilu Ijọba Gẹsi ṣẹṣẹ fọwọ si iwe adehun kan pẹlu awọn Ijọba Faranse lori ọna ọkọ ofurufu ti nwọn yio ma jọ lọ si Australia. Irin kan bi oje ni nwọn fi ṣe awọn ọkọ ofurufu iru eyi ti ẹnwo aworan rẹ ninu iwe yi. Ọgọrun enia ni ọkọ na a ma ko, yio si ma sa pasa ninu ere.

# Bawo Ni Olympio Se Ku Lori Oro Ilu Togo....?

Ti o ba de ilu Lomẹ ni owurọ yi, o ko le tete ri 'banku", tabi "Kẹnki" ra lọwọ Anti Amba tabi Mami Kweku nitoripe gbogbo awọn obinrin ilu Togo mọ awọn ọkunrin ilu na ni wọn nṣe ọ f ọ alamojuto ilu na Dokita Sylvanus Olympio ti a w ọ n ọlọtẹ kan yin'bọn pa laipẹ yi lọwọ nitoripe awọn kan ni Ijọba rẹ ko tẹ awọn lọrun to.

O ku osu mẹta loni ki o di ọdun mẹta gbako ti ilu na ti a npe ni TOGOLAND gba ominira lọwọ a w ọ n Oyinbo Faranse (French) ti nwọn ti nmu wọn sin lati ọdun gọbọyi.

## IGI—IWE

Dokita Olympio y i jẹ ọjọgbọn ti o mọ iwe pupọ o si gbọ ede Oyinbo to mẹta; iyẹn ni w i p e o gbọ Gẹsi, ede Faranse ati ti awọn Jamani (Germany) paapa. Lẹhin eyi o gbọ ede Yoruba nitoripe o fi igba kan se isẹ ni Eko nibi, ki a ma sẹsẹ sọ ede bi mẹta ti o gbọ ni t i awọn a r a ilu rẹ.

**LATI OWO**
**OLOFINTOTO**

Ki a pa ti ẹkọ ijinlẹ t i alamojuto ilu Togo n i mọ ti sibikan, Dokita Olympio mọ ilu awọn alawọ-funfun bi ẹni m'ọwọ nitoripe gbogbo ilu ti a npe ni England, Germany, France, Austria, Suweden ati Holland ni o de nigb ati o nkọ ẹkọ giga nilu Oyinbo ki o le mọ bi nwọn nṣe lo igbesiye wọn si nibiti oju ti la.

O si kọ ẹkọ pataki n i n u irin ajo rẹ na.

## Ogun Ajakaiye

Nigbati ogun ajakaiye bẹ silẹ ni iwọn nkan bi ọdun mejilelogun, awọn Oyinbo Franse ni ki nwọn wa Dokita Olympio kuro nilu lọ si ilẹ Dahọmi (Dahomey) nitoripe awọn fura sii wipe ẹhin awọn Ijọba Gẹsi ni o wa, o si le koba awọn ninu rogbodiyan ogun na.

Gbara ti nwọn ti daa silẹ s i l ẹ ninu igbekun ihamọle ti ogun yi ni o ti pinnu wipe isẹ osẹlu ni on yio se ki on le gba awọn a r a ilu on kuro loko ẹru awọn Faranse.

Eyi si jẹki o da ẹgbẹ osẹlu tirẹ silẹ ni kiakia, nwọn si fi se alaga ile igbimọ asofin i l u Togo ni ọdun 1955. Nigbati asiko to fun idibo awọn ọmọ ẹgbẹ osẹlu tirẹ ti o njẹ TOGO UNITY PARTY (TUP) ni nwọn wọle, nwọn si fii jẹ alakoso ijọba ilu Togo.

Tẹlẹtẹlẹ, ẹgbọn iyawo rẹ t i o n j e Nicholas Grunitsky (ti awọn ọlọtẹ pe pada l se ti o koja nibiti o ti lọ f'ori pamọ si, wipe ki o wa se ọpomulero ijọba) ni o ti n s e alakoso ijọba ilu Togo ri ki nwọn to dibo.

## EDE AIYEDE

Mo gbọ wipe eto oruko ti awọn ọmọ ẹ g b ẹ osẹlu ti Ọgbẹni Grunitsky pelu a w ọ n ọ m ọ ẹgbẹ ọdọ kan ti oruko w ọ n n j e JUVENTO PARTY ti se, ti ko yanju geere ni o ko ba wọn nibi idibo na ti o jẹ ki nwọn fori gbagi ni ọdun kẹta ẹhin.

Ko si enikan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Juvento na ti o wọ'le ibo sibẹsibẹ abẹ wọn ko se fi ọwọ rọ sẹhin lọdọ awọn ara ilu Togo. Iyẹn nipe ọpọlọpọ awọn ara ilu ni ọdọmọde ni nwọn nfẹ ti awọn ẹgbẹ osẹlu na.

Awọn ẹgbẹ osẹlu ti ọdọmọde ti a pe ni JUVENTO PARTY yi ti fi igba kan jẹ amugba-lẹhin fun a w ọ n ọmọ ẹgbẹ osẹlu ti Dokita Olympio ti a pe oruko wọn ni TOGO UNITY PARTY, ede aiyede kan ni o bẹ silẹ ni arin wọn nigbati awọn ọmọ ẹgbẹ JUVETO na sọrọ kan lati fi tako Ijọba wọn. Ọrọ itako na di ijangbọn, eleyi mu ki Ijọba Olympio fi asẹ gbe ẹgbẹ ọdọ na bi jiga wipe nwọn ko gbọdọ gbọ oruko wọn mọ nilu.

Ọpọlọpọ awọn ti o jẹ asiwaju ninu ọmọ ẹgbẹ Juvento na ni nwọn si ko da sẹwọn; awọn bi loya Merait Santos (tise minisita alamojuto idajọ ododo) ati Ọgbẹni A. Meatchi, iyen sa lọ f'ori pamọ si Ghana nigba na. Minisita kan ni Ọgbẹni Meatchi nigbakan ri ki o to sa ti'lu silẹ, nwọn si ti tun sọ ọ di Minisita pataki lọsẹ ti o koja yi nigbati o tun pada wọlu lẹhinti a w ọ n ọlọtẹ ilu Togo ti pa Olympio tan.

Ẹ o mọ gbọ iyoku ninu iwe yi lọsẹ tombọ ni kikun.

# Malu Ti Ko Niru..?



**Aworan yi n'i malu kan ti nwon so wipe on ni nwon ri wara pupo gba lara re nilu Oyinbo nibiti nwon g b e lo se afihan awon afunwara ni London; malu yi ni o si gba ebun lori eyi.**

# ELETI–OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI LEJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosọko Street, Lagos, "ELETI—ỌFẸ" LAGOS

P O. Box 468 Phone 23370

VOL XIV. No. 855 SATURDAY JAN: 25, - FEB. 1st 1962


# Tisa Opuro...

Awọn agbalagba wa ni aiye atijọ ko ko iyan ọrọ otitọ kere tobẹgẹ ti nwọn fi ni ọpọlọpọ owe lori a nsọ otitọ na, ọkan ti o si jẹ pataki ikilọ ninu awọn owe wọn na lori otitọ sisọ ri : "ILE ti A BA fi ITỌ mọ, IRI ni YIO wo o".

Gbogbo ẹniti o ba jẹ Oloye l'ọkunrin ati lobinrin a mọ wipe otitọ ni ọrọ owe na ko si fi igba kan yẹ ri, iyẹn ni olori ọrọ awa onirohin Eleti-Ọfẹ ti a o fi gba yin ni iyanju ninu ọsẹ yi, paapa ẹnyin o b i ti ẹ ni awọn ọmọ ni ile-ẹkọ ni ode isisiyi.

## Omo Ilewe..

Lati bi ọdun melo sẹhin ni a ti ngbọ irohin kakiri Ipinlẹ Ila-Orun wipe ọpọlọpọ awọn ọmọ ile-ẹkọ ni nwọn nfi owo ra IWE-ẸRI MO - yege NINU-ẸKỌ mi (School Certificate) kakiri lọdọ awọn TIṢA OPURỌ ti nwọn ko kọ ki aiye ko bajẹ.

Eleyi ko tun tẹ wọn lọrun, wọn tun fi igba kan bẹresi ma sọ fun awọn obi ọmọ ile ẹkọ na kakiri wipe awọn le ba wọn ra iwe-idanwo ni orisirisi ti yio fi jẹ ki ọmọ wọn yege lai ja fefe ninu ẹkọ ti o kọ ninu ile'we rẹ ki o le ri isẹ atata ṣe ti o ba jade ninu ile ẹkọ na.

## Onijibiti

Ọpọlọpọ awọn tiṣa (Olukọni) ni o ti fi ipa ọna eru yi di olowo di ọlọrọ, eyi si jẹ ki awọn tiṣa ati akọwe wọn ni ilẹ Yoruba paapa bẹresi tọna ti ko tọ yi lati ma gba owo-ẹhin lati le ma ta iwe idanwo ni aṣiri fun awọn ọmọ ilewe na ki ọjọ idanwo to de.

Ẹnyin obi, iru awọn ọmọ ti a fi iwe eru bayi kọ lati ibẹrẹ igbesi aiye wọn, nigbawo ni wọn yio dagba tan ti nwọn ko ni ma lo iwa jibiti jaiye wọn kakiri! Ti ẹ ba ṣe akiyesi irohin awọn onijibiti ti njade lojojumọ ninu iwe kakiri ti awọn ọmọ ti o ṣẹṣẹ jade ninu ilewe ni o pọ nibẹ.

Bi nwọn ba gba wọn sibi iṣẹ, ọna lati ko'wo jẹ ati lati yi iwe-owo pada ni nwọn a ma wa kiri bara bara nitoripe gbogbo wọn ni nwọn fẹ tete kọ'le ti nwọn si fẹ ra moto – ayọkẹlẹ.

Bi nwọn ti nfi eru ko owo wa sile lati ibi iṣẹ ni inu awọn obi wọn ndun si i nitoripe ọmọ wọn "KO WA SAIYE TI O LE" rara ṣugbọn aye f'ẹwọn l'ogba ni nwọn wa.

Ki a maṣe gbagbe wipe awọn ọmọ ti a n k ọ ni ọna jibiti lọjọ oni ni yio di agbalagba lọjọ ọla, t nwọn yio si fẹ sọ wipe awọn yio di alakoso Ijọbai ilu. Ṣe ọna jibiti ti nwọn yio ma gba ṣe ilu lọjọ ọla na niyi ? Ẹru mba wa o!

Ẹnyin obi, ile ti a ba fi itọ mọ, iri lo ma nwo o, ẹ ye fi owo ra iparun fun awọn ọmọ nyin.

# Iwe Si Olotu

## ITAN "INU ELETI-OFE" DUN

Olotu, ẹ jọwọ ẹ tubọ mo ba wa tẹ orisirisi itan ti ẹ ntẹ fun wa ninu iwe iro-Eleti—Ọfẹ nigbagbogbo si.

A fẹ ki ẹ mọ wipe a ngbadun awọn itan ti awọn onitan yin kọ nipa ilu Eko, awọn ara Eko atijọ pẹlu bi oju ọna ti ri; itan igbesi-aiye Ọba Alake Ademọla Keji ti o ṣẹṣẹ waja t i Ọgbẹni ỌMỌ ABATI n k ọ p ẹ l u itan awọn alapata ẹran ti Alhaji Ojikutu nfi igba kan kọ ti a k o t u n r i ipari rẹ mọ.

Boya ẹ ko mọ wipe ọpọlọpọ ọgbọn ati lakaye ni a nri kọ ninu awọn itan na. Ẹ jọwọ Olotu k o ni rẹ yin, ki ẹ tun ma fun wa ni orisiri itan si.

Emi ni,
A. Ojẹkunbi,
Sango,
Agege


**E ma ka iwe Iron Eleti--Ofe ti o kun fun Irohin A l a d u n**



Advert. NO. 8.

## Federation Of Nigeria Fourth Development Loan

The Central Bank of Nigeria has been authorised by t h e Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £15 Million registered Stock in February, 1963. The Stocks to be issued will be:-

1. £2 Million 5o/o Federation of Nigeria Fourth Development Stock 1968-to be repaid in full on 5th August, 1968.
2. £3 Million 51/4o/oFederation of Nigeria Fourth Development Stock 1972-to be repaid in full on 5th August, 1972.
3. £10 Million 53/4o/o Federation of Nigeria Fourth Development Stock 1987-to be repaid in full on 5th August, 1987.

The three Stocks will be issued at par in multiples of £10 and applications w i l l be accepted at banks throughout Nigeria or at the offices of the Central Bank in Lagos and Kano u p t o the close of business on 5th Febuary, 1963.

Prospectuses, which contain full information and application forms may be obtained from banks and Stockbrokers or at the Central Bank's offices in Lagos and Kano up to the close of business on 5th Febuary, 1963.

W. A. TIBBLES,
GENERAL MANAGER.
CENTRAL BANK OF NIGERIA.
JANUARY 1963.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## ODUN JUBILI

Ninu oṣu yi, iranti aj'ọdun Jubili mẹta ni mo dupẹ lọwọ ẹlẹda mi ti o da mi si ti nwọn ṣoju mi; ikinni ni ti ile ẹkọ giga ti nwọn npe ni Eko Boys' High School ti o wa ni Maṣẹwele ni Muṣin nisisiyi; ekeji ni ti awọn igbimọ ti o da owo pepa silẹ fun wa ni ilu yi (West Africa Currency Board); ẹkẹta ni ti ile iwe giga ti Ijẹbu-Ode (Ijẹbu-Ode Grammar School).

## Omo Eko

Ẹnyin ọkawe mi, ọrọ ile ẹkọ giga ti awọn ọmọ Eko ti nwọn npe ni Eko Boys High School yi ni ma kọ fẹnu kan, ẹ maṣe si mi gbọ! Awọn ọmọ Eko nikan kọ ni Alufa (Rev) William Benjamin Euba da ile'we na sile fun nigbati oju iṣẹ ọga tiṣa Wesleyan Boys High School ti o ti nṣẹ silẹ ki o to da eyi ti o wa ni Maṣẹwẹle ni ọdun yẹn lọhun.

A ko le darukọ Alufa Euba ki a ma darukọ Ọgbẹni Obadiah Edward Roberts, tiṣa ti o sin ilewe giga yi de ibiti ẹru ko le ba mọ. Mo mọ diẹ ninu awọn ti nwọn ti di PA l'Eko lọjọ oni ti o jẹ wipe le'we yi ni nwọn ti ka iwe, awọn na ni bi Adajọ agba Kotu awọn ọlọpa Ọgbẹni Adebiyi Desalu, Adajọ agba Victor A. Savage ti o wa ni ilu awọn Ibo nisisiyi, adajọ A. O. Lapitẹ, Loya Magnus William, Adajọ agba Richard Daherty ti o wa ni Ibadan ati awọn enia enia bẹbẹ ti aye ko si lati darugbogbo wọn,

## Omo Obanta

Mo tun ba awọn ara Ijẹbu- Ode (Ọmọ Ọbanta) yọ fun AJỌDUN JUBILI ti nwọn da ile'we giga-Ijẹbu-Ode Grammar School silẹ. Adọta ọdun kiṣe ọmọde ọjọ eleyi mu mi ranti awọn ọga ilewe na latijọ, awọn bi Alufa Gansallo; Alufa (ti o di Biṣọbu nigbehin) Phillips, Alufa I. Oludọtun Ransome-Kuti ("Duwodu" o ṣe bẹbẹ fun awọn ọmọ Ijẹbu nipa ẹkọ ijinlẹ) Ẹni-ọwọ A.A. Ẹfunkọya o gbalẹmi ni alejo l'ọdọ rẹ ninu ile-iwe na ni ọdun 1938 nigbati mo lọ ki Ọba Gbelugbuwa pẹlu Dokita Olusẹgun.

Ọmọ Ọbanta, ẹ ku ajọdun o!!

## Owo Eyo

Nipa ọrọ owo silẹ ti a nna nisisiyi, mo gbọ wipe o di adọta ọdun nisisiyi ti awọn Oyinbo ọga wa atijọ ti ko wọn wa fun wa fun lilo dipo owo-ẹyọ ti awọn baba wa ti nna nlo ri. O yẹ ki a dupẹ lọwọ awọn Oyinbo na nitoripe emi ba owo-ẹyọ laiye;

(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)



"BI IWỌ BA NWÁ ASIKI FUNRA RẸ"

[illegible]



[illegible]



...wọ ha nwa asiki funra rẹ bi?

...i yio pẹ lọ titi fun ọ bi o ba nfi owo pamọ

...tigba dẽgba nile ipamọ owo ti Barclays

Owo rẹ nbẹ labẹ abo lọwọ Barclays. Ki yio gbọna atipe bi o ti npọ nibọ si bẹni yio ma lọsi. Lọ bẹre nibiṣẹ Barclays tombẹ nitosi ọdọ rẹ nipa fifi owo pamọ ki o si bẹrẹ lati ṣe bẹ ni kiakia.

[illegible]

BARCLAYS BANK D.C.O.

# Itan Oba Alake Ademola Keji

## (Lati Owo Omo Abati)

### OMINIRA EGBA

Gẹgẹbi mo ti sọ fun nyin nigbati mo ṣẹṣẹ bẹrẹ itan mi wipe nigbati awọn Oyinbo gẹsi de ba awọn Ẹgba ninu idẹra ominira ni nwọn ba wọn.

Awọn agbalagba ologboni ni atiṣe ilu wa lọwọ Awọn ologboni'ṣna' si fi gbogbo nkan s'eto; uwọn ni ẹru lara

Lẹhin ti Ọba Gbadebọ ti ilu Oyinbo de ni 1904 gbogbo nkan mere-mere ti o ri ti awọn Oyinbo ṣe si ilu wọn ni on na fẹ ṣe si ilu Abẹokuta ṣugbọn gbogbo rẹ ọrẹ owo ni ko si si Ijọba kan ti o le gbe ori laisi owo lọwọ. Ọrọ wa di wipe nwọn ni lati ṣe ofin ki ara ilu ma san owo-ori fun Ijọba wọn ki nwọn le ma ri nkan lo lati fi tun ilu ṣe

Nkan ti ọrọ ogun Ijẹmọ da silẹ fun awọn Ẹgba ni nkan bi burẹku pọ. Ogun yi sọ ọpọlọpọ di alaini baba Ọrọ Ogun Ijẹmọ na ni o si fa Ijọba Ẹgba ti o jẹ Ọlanrewaju sẹhin. Nitoripe lẹhin ogun na ni awọn Ijọba Gẹsi gba ominira lọwọ awọn Ẹgba.

### Ogun Adubi

Awo lebira onisẹ ọba ko wọpọ, bẹ Ijọba si n ati lo enia lati tun ilu ṣe. Eleyi si jẹ ki awọn ọlọpa ma mu awọn ara ilu ṣe iṣẹ apapandodo. Nwọn ko ti a nmu ni ṣe iṣẹ nipa yi mọ ni arin ilu nikan, nwọn tun gbe wahala na lọ ba awọn Ẹgba ni arọko.

Lori ogun Adubi ti awọn Ẹgba ja ni iwọn nkan bi ọdun marundiladọta sẹhin yi lo mu awọn lebira ti o ntun oju irin reluwe ṣe ninu ọdun 1920 ti nwọn fi egungun "WONWẸ" da ara wọn lara da orin yi silẹ bayi :-

"Ogun Adubi soju mi ja,  
Baba rẹ wa pa ṣọja meji,  
Pa ṣọja meji l'abule wọn,  
Iyawo rẹ nsalọ bi aparo,  
Iwọ na wa mbẹlọ bi igala. ",

Ọdun kẹtalelogoji ti nwọn ti nkọ orin na kakiri arọko Ẹgba niyi, ki ọkan ninu awọn akọrin l'Abẹokuta to ṣẹṣẹ wa kọ fun awọn ti o nṣe awo orin olugboun (gramaphone record) ti nwọn nkọ kiri ilu Nigeria nisisiyi.

Lẹhin nwọn pari ogun Ijẹmọ yi ni awọn Ijọba Gẹsi ba gbe ofin kan jade wipe awọn ko gbọdọ ri ibọn "ṣakabula" ni ọwọ ẹnikan mọ ni arin ilu Abẹokuta ati gbogbo arọko awọn Ẹgba Eleyi mu wahalaba awọn agbẹ loko nitoripe ibọn ṣakabula yi ni nwọn nlo lati fi pa

awọn ẹranko ti o mba wọn ni nkan ọgbin ti nwọn gbin si oko wọn jẹ.

### Ojokoro

Waha a yi ti awọn ọmọ Ẹgba awọn bi Ologbe Pa J.K. Coker (ọmọ Ajọbọ) ati Ologbe lọya Eric Ọla wọlu Moore (Ọmọ Burada) Dokita Savage ati Philip Taiwo Coker dide si ọrọ na lọdọ Gomina ni Eko ki nwọn to yi ofin na pada ni lati ko ibọn onibọn fuu wọn.

Ariwo ogun Adubi le ju ti Ijẹmọ lọ nitoripe awọn Ẹgba ti fi akekọri wipe kii ku ni ẹmeji. Ninu ija Ogun na ni nwọn pa Ọba Ọshinlẹ Karunwi, nwọn si fi oju awọn ṣọja Hausa ti nwọn ko wa ti mọmọ ni arọko. Bi nwọn ti nyin bọn ṣakabula si nwọn ni nwọn tun nlo ogun majele ba wọn ja. Nwọn pa Oyinbo onisowo kan ni apafọn ni Teṣan Wasinmi nibiti o gbe ti nra epo ati ekurọ.

Awọn ara abule kan ro ọgẹdẹ ti o pọn daradara silẹ fun awọn ṣọja, awọn ti o jẹ wọn filẹ faṣọ bora ni kiakia. Awọn Ẹgba ko hu iwa yi lati fi iwa ọdaju han, awọn ṣọja ti nwọn lọ ba wọn ni arọko ti nwọn bẹrẹsi pa wọn ni ipakupa ninu oṣu May mọ June 1918 ni o fa sababi.

Gbogbo igba rogbodiyan yi Ologbe ọba Ademọla Keji wa ni abule kan ti nwọn npe ni OJOKORO leti Oko Ọba ni agbegbe Agege nibiti o gbe ti nṣe iṣẹ agbẹ on pẹlu awọn Pa Jibowu (baba Ologbe adajọ Jibowu) sugbọn bi gbogbo nkan ti nlọ si ni ilu Ẹgba ni ọba yi ngbọ. Oba Gbadebọ ni o wa lori itẹ ngbana.

(Iyoku di ọsẹ ti mbọ)

# ETI-OFE D'araba



**Lady Tweedsmuir, Menbe. of Parliament for Aberdeen, Scotland, has been appointed Parliamentary Under Secretary of State at the Scottish Office.**

**Lady Tweedsmuir was born in 1915 and has been a Member of Parliament since 1946. She has three daughters and is married to Lord Tweedsmuir, a govenor of the Commonwealth institute.**

# Memorial Service For Alake In London

LONDON — A SPECIAL memorial service was held at the early eighteenth century Church of Saint Martin's-in-the fields, Trafalgar Square, London, yesterday, for the late Alake of Abẹokuta, Sir Ladapo Ademola.

The Alake, who died on December 26, aged 90, reigned in Abeokuta for over 42 years.

As a prince, he visited England and received the gift of a Bible from Queen Victoria.

He was awarded a knighthood when Queen Elizabeth toured Nigeria in 1956.

The Acting High Commissioner for the Federation of Nigeria in Britain, Chief Arthur Prest read the lesson at the service which was well attended by prominent people including Governors who had served in Nigeria.

## New Asbestos Plant For Enugu

LONDON

"Good progress" in the construction of the asbestos cement factory at Enugu is reported by the chairman of Turner and Newall Ltd., Mr. R.G. Soothill, in his annual report published in London yesterday. Production was expected to start before the end of March this year.

The factory is being built for a subsidiary company, Turners Asbestos Cement (Nigeria) Ltd., and this will provide more work for people in the Eastern Region.

# Three New U.A.C. Textiles Managers

LAGOS— Textiles Division of the United Africa Company of Nigeria Limited has announced the promotion of three members of its staff to management status with effect from January 1 this year. They are Mr. C.P.N. Udeagu, aged 31 years,

Mr. Udeagu, joined the Company in 1952 as a junior clerk in Kano and had served in different capacities in various stations.

Mr. Nwajei joined the Company in 1942 as a probationer in the District Manager's Office, Jos. He rose to the post of Senior Clerical Supervisor in 1961 and later that year was appointed acting Sales Manager.

As for Mr. Onelum he entered the Company's service in 1951 and was attached to the District Manager's Office, Warri as Lloyds Survey and G.A. 6 Clerk Since his appointment he served in various positions until 1961 when he was transferred to Benin as Acting Textiles Manager.

**Comfortable and safe**



A roomy 5-6 seater, space for lots of luggage, luxurious appointment, excellent finish, a very high standard of safety, these and many other welcome features you find in both of the 190 models and besides the 190 Diesel offers quite exceptional economy. Let us demonstrate by a trial run, free of any obligation, what excellent value these cars represent.

MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS . IBADAN . KANO . KADUNA . JOS . PORT-HARCOURT . ABA

Sub – Distributors :

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY . ONITSHA . ABA

# Oro Ayiluka

(O bẹrẹ loju ewekarun)

### Owo Fyo

ỌKẸ KAN ni a ma ndi ṣi e marun si (ti mo ba mba iya mi lọ sọja), eyiti a nti bọ apo ẹwu nisisiyi. Awọn iwọfa iya mi ni o ma nru awọn owo na, aru -lagun si ni riru owo na jẹ fun wọn.

Ṣe ẹnyin na wa ri wipe awọn Oyinbo ti sọ aiye dẹrọ nipa ọkẹ-owo kan ti a nti bọ apo ẹwu nisisiyi Ki akoko tuntun ti owo tuntun yi ki o sa wa o, ki ani lọwọ ki a mọ ni lọrun.

### Yigi Awe

Mo gbọ wipe ti awẹ ba ku fẹrẹfẹ orisirisi igba yigi ni awọn ti nwọn ba bi ọmọbinrin ma ngba. Ni ọsẹ ti o kọja awọn Lemọmu ba wọn so yigi kan ni Oke-Popo, ikan ni Idoluwo, ikan ni Olowogbowo, eyiti o wa pa bambari ni ti Ọmọbabinrin kan ni Iga Ọba Adele, ti ẹlẹyinjuẹgẹ Mojiatu ọmọ Ọba Adele ti nwọn gbe niyawo fun Ọgbẹni A. O. Mustafa, ọga kan nibi iṣẹ awọn Munisifa l'Eko. Mo gbọ wipe awọn enia jankanjankan lo kun bẹ, ọti ati iresi si pọ jaburata nibẹ ṣugbọn o dun mi ti nwọn ko pe emi Ayiluka si ELEKO REST; ti awẹ ba pari ma lọ ki wọn fun nkan alejo temi.

Mojiatu, ọmọ Onikoyi, ọmọ Ọbalufọn, ile ọkọ na a san ẹ o, ẹ si ki opo Awẹ yi o! Ẹmi yio gbaa ja o!

# Awon Soja Togo

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

### Ijoba Dimeji

Ọgbẹni Gruntzky paapa ṣe bẹbẹ, on na ra awọn ikọ tirẹ alara wa si ipade gbogbo Ijọba apapọ orilẹ ede Afrika ti'nwọn nṣe lọwọlọwọ ni ilu (Eko) ni ana, o ni on ko le jẹ ki awọn toju on ka awọn ọmọ ẹgbẹ on m'ẹbọ; awọn enia ti nwọn jẹ ti Ijọba Ologbe Olympio paapa fi awọn ikọ ti wọn na ranṣẹ si ipade na l'Eko. Ni ile-ero ni OKUN-ALASIA ni gbogbo wọn gbe wọ si.

Nigbati awọn ikọ Ijọba mejeji ti o wa ni ilu Togo nisisiyi de ile apejọ ipade na ni alẹ ana, olukuluku wọn ni o fi ẹdun rẹ fun ijoko igbimọ na, nwọn si ro ẹjọ wọn sibẹ nipa nkan ti o fa iku Olympio ni ilu Togo.

### Omo Tuntun

Awọn kan ni ọna ti Ọgbẹni Grunitzky fẹ fi rọ ofin eto iṣelu Togo s'apa kan ti o fẹ ma ṣelu lọ lai dibo ko tọna rara. Nwọn ni awọn Oyinbo Faranse pelu awọn ara ilu Ghana ni o wa lẹhin awọn ọlọtẹ ti o pa Dokita Olympio. Nwọn ni awọn ri gbangba wipe lati ilu Ghana ni nwọn ti fun wọn ni owo ati ibọn pelu ahaya ti nwọn lo nibi ọtẹ na.

Awọn ikọ keji ti nwọn jẹ aṣoju Ọgbẹni Grunitzky ti awọn ọlọtẹ ṣẹṣẹ fi ṣe alakoso Ijọba Togo ni nkan ti o ṣẹlẹ nilu awọn ko nṣe ọrọ ara ita rara, awọn fẹ ki nwọn gba ọrọ ẹsun ti awọn ṣọja ti o fi agbara gba ijọba lọwọ Olympio gbọ. Bi awọn Oyinbo Faranse ati ara Ghana lọwọ nibẹ awọn ko le sọ rara.

Akọbi ọmọ Ologbe Olympio ti o njẹ Bonito paapa ti de si Eko lana.

Irohin ti a tun gbọ loru ana lati bode Aflao nibiti awọn ara ilu Nigeria ro si lati kọja si Ghana ti nwọn ko ri ọna kọja, ni ti awọn aboyun ti nwọn bi ọmọ tuntun. Nwọn ti ko awọn ọmọ na pẹlu iya wọn lọ si ile alabiyamọ ni Lomẹ fun itọju.

# E ka

## Iwe Irohin Eleti Ofe Losose

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company. 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370
EDITOR (OLOTU) ỌLA ỌNATADE
15, Kosọkọ Street, Lagos.

# Ogbeni Ara Ilu Wales



**Ogbeni Nick Whitehead ara ilu Wales ti e nwo ninu aworan oke yi ni a gbo wipe o ni emi a-sa-pe pupo nibi ere sisa, on ni o si se asoju awon ara ilu re nibiti nwon gbe ti lo sare agbaiye ni ilu Australia laipe yi.**